**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (3)**

**Ìjẹ́wọ́: 3 Jòhánnù 2:** Olùfẹ́, èmi n gbàdúrà pé nínú ohun gbogbo kí ó lè ma dára fún ọ, kí o sì ma wà ní ìlera, àní bí ó ti dára fún ọkàn rẹ.

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Jésù Olúwa, jẹ́ kí agbára àjínde Rẹ bà lé gbogbo agbègbè ayé mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
2. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, bẹ̀ mí wò pẹ̀lú àmì àti àrà Rẹ, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa igbàgbọ́, mo fọwọ́kan ìṣẹ́tí aṣọ Jésù, mo sì gba ìwòsàn pípé mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
4. Àìsàn ìyówù nínú àgọ́-ara mi, di gbígbọ̀n jáde nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìkórajọ̀pọ̀ àjẹ́, níbi tí wọ́n ti n rán ibi sínú ayé mi, jó, kí o sì run pátápátá nipa iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
6. Àgọ́-ara mi, gba iná Ẹ̀mí Mímọ́, kí o sì jo gbogbo gbòngbò ìpọ́njú nínú ayé mi run, ní orúkọ Jésù.
7. Mo dúró lòdì sí gbogbo ẹ̀mí ìpọ́njú tó n rúnú lòdì sí ayé mi nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
8. Bàbá mi, nípa ọ̀rọ̀ ìmúpadà-bọ́-sípò Rẹ, jẹ́ kí ìmúpadà-bọ̀-sípò àwọn ohunrere tímo ti sọnù sẹlẹ̀, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, nípa agbára nlá Rẹ, mo tẹrí agbára tó nfa ìrora sínú ayé mi ba, mo sì jáde kúrò nínú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tó lágbára àti ẹni tó dára si i, ní orúkọ Jésù.
10. Mo pàṣẹ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo òṣì àjogúnbá tó n ṣàn nínú ìdílé mi yóò di aláìlágbára lórí mi, ní orúkọ Jésù.

11. Mo yọ ara mi kúrò nínú onírúurú ìdádúró ohunrere ti agbègbè, tó n ṣàn nínú ìpìlẹ̀ mi nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo àṣopọ̀ òkùnkùn, tó n tọpinpin ìrora àti ìjìyà nínú ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, wòmísàn, èmi yóò sì sàn àn, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fi ayé mi ṣòfò, ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
15. Bàbá mi, jẹ́ kí àmì àti àrà farahàn ní gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ìdíwọ̀ t'ara àti t'ẹ̀mí sí àwọn alàjá tí mò n retí, di mímú kúrò nípa iná, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo àmì ibi tó n dá ilẹ̀ ìlérí tí mò n fẹ́ dúró, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo ibùjókò ìkùnà ayé nínú ayé mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ìránṣẹ́ àìláṣeyọrí nínú ayé mi, já ìdè rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
20. Mo gba àjẹsára atòkèwá lòdì sí onírúurú àìsàn, ní orúkọ Jésù.
21. Ohun ìjà ìyówù tí wọ́n ṣe lòdì sí àláfíà mi, kú, ní orúkọ Jésù.